


*Lánre Mákindé jẹ́ Olùkọ́ nípa Ọgbọ́n Ìkọ́nilẹ̀dè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè abínibí àti èdè àkọ́kúntẹni ní Ẹ̀ka ìmọ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù, Yunifásítì Ìpínlẹ̀ Èkó (LASU). Bẹ́ẹ̀ ni kò sì kẹ̀rẹ̀ nípa kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní Ọgbọ́n Ìkọ́ni ní Lítíréṣọ̀ èdè Yorùbá. Ṣíwájú, sí i, kò gbẹ́yìn nínú ìmọ̀ kọ̀ríkúlọ́ọ̀mù àti bí èyí ti jẹ mọ́ ẹ̀kọ́ èdè. Akéwì Akọ̀wé ni, ó sì máa ń fi èyí dá àwọn ọ̀rẹ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ lára yá bí ọwọ́ bá dilẹ̀.*

*Lánré Mákindé ti ṣe iṣẹ́ ìwádìí mélòó kan lórí ẹ̀kọ́ Lítíréṣọ̀ àti èdè Yorùbá àti àwọn èdè Nàìjíríà lápapọ̀. Lára àwọn ìwé àpilẹ̀kọ àti àbọ̀ ìwádìí rẹ̀ ni a sì ti gbé jáde nínú àwọn ìwé àtìgbàdégbà (Jọ́nà) mélòó kan. Ó ti kọ àwọn ìwé wọ̀nyí: Ọgbọ́n Ìkọ́nilédè Yorùbá; Teaching The Language Skills in Yorùbá àti ìwé ìtàn àròsọ tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́, Aṣeni ń ṣera ẹ̀.*


**ISBN: 978-35211-3-6**

*A tẹ ìwé yìí ní*
BAES OLATUNJI PRESS & BOOK INDUSTRIES
3, Adédoyin Street,
Near Oláleye Market,
Via Shipeolu Street,
Palm Grove, Lagos.

ÌLÒ ÈDÈ YORÙBÁ FÚN OLÙKỌ́ ÀTI AKẸ́KỌ̀Ọ́

# ÌLÒ ÈDÈ YORÙBÁ FÚN OLÙKỌ́ ÀTI AKẸ́KỌ̀Ọ́

Èdè Yorùbá




Lánre Mákindé

# ÌLÒ ÈDÈ YORÙBÁ

# FÚN

# OLÙKỌ́ ÀTI AKẸ́KỌ̀Ọ́

Lánre Mákindé

# Copyright

© Lanre Makinde 2000

All rights reserved No part of this publication may be reproduced, stored in a refrieral system, or transmitted in any form or by any means, electronic, mechanical, photocopying, recoding or otherwise without the prior permission of the author.

First Published 2000

A te iwe yii ni
BAES OLATUNJI PRESS & BOOK INDUSTRIES
3, Adediyin Street,
Near Olaleye Market,
Via Shipeolu Street,
Palm-grove, Lagos.

ISBN 978-35211-3-6



## ỌRỌ̀ ÀKỌ́SỌ

Ìwé atọ́nisọ́nà nípa bí a ṣe lè lo èdè Yorùbá lọ́nà tó pegedé ni a ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ nínú ìwé-ìléwọ́ yìí. Fún akẹ́kọ̀ọ́ tí ó ń kọ́ èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè àkọ́kúnteni, pàtàkì ni ìwé yìí jẹ. Bákan náà ni ó sì wúlò fún àwọn olùkọ́ tí ó ń kọ́ àwọn alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ní èdè Yorùbá.

Ọpẹ́lọpẹ́ ẹ̀jìká ni kò jẹ́ kí aṣọ ó yẹ̀. Iṣẹ́ àwọn Bàbá mi àti àwọn Ẹ̀gbọ́n mi nínú ìmọ̀ Èdè Yorùbá ló ràn mí lọ́wọ́ láti gbé ìwé-ìléwọ́ yìí jáde. Díẹ̀ nínú wọn ni, Ọ̀jọ̀gbọ́n Afọlábí Ọlábọ̀dé, Ọ̀jọ̀gbọ́n J.O.O. Abíri, Ọ̀jọ̀gbọ́n P.O. Ògúnbọ̀wálé, Alàgbà Táíwò Olúnládé, àti Alàgbà Olúfẹ́mi Àbàtì.

Bí a bá rí àṣìṣe nínú ìwé yìí, kì í ṣe ti àwọn àgbà ọ̀jẹ̀ tí a yẹ iṣẹ́ wọn wò, tiwa ni.

Kò sí àníàní pé ìwé yìí yóò jẹ́ kòṣeémánì-ín fún gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkọ́ èdè Yorùbá.

Láńre Mákindé.

# ÌTỌ́KA


| Orí | Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ | Ojú Ìwé |
|---|---|---|
| Orí Kìn-ín-ní: | Ìró Èdè Yorùbá | 1 |
| | Àwọn Alífábẹ́ẹ̀tì | 1 |
| | Fáwẹ̀lì àti Kọ́ńsónáǹtì | 2 |
| | Ìró Ohùn | 6 |
| | Ìhun Sílébù | 12 |
| Orí Kejì: | Ìsọrí Ọ̀rọ̀ àti Àpólà | 15 |
| Orí Kẹta: | Àkọtọ́ Òde-Òní | 29 |
| Orí Kẹrin: | Èdè Yorùbá àti Ìwúlò rẹ̀ | 37 |
| Orí Karùn-ún: | Àròkọ Kíkọ | 51 |
| Orí Kẹfà: | Àwọn Èròjà Amédèdùn | 62 |
| Orí Keje: | Èdè Àmúlò | 86 |
| Orí Kejọ: | Kókó Ọ̀rọ̀ Lórí Àkàyé | 94 |
| | Kíkọ Ìwé Apè, Ìkéde abbl. | 95 |
| Àwọn Ìbéèrè Fún Ìdánwò | | 100 |
| Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí | | 102 |




# ORÍ KÌN-ÍN NÍ
## ÌRÓ ÈDÈ YORÙBÁ

Kí ó lè rọrùn fún wa láti ní òye kíkún nípa àpadé àti àludé èdè Yorùbá, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá èdè yìí ní fẹ̀ẹ̀rẹ̀jógí.

(1) Àwọn alífábẹ́ẹ̀tì Yorùbá ni:

a b d e ẹ f g gb h i j k l m n o ọ p r s ṣ t u w y. (25)

(2) A lè pín àwọn alífábẹ́ẹ̀tì sí :

(a) Ìró fáwẹ̀lì (vowels)

a, e, ẹ, i o, ọ u, an, ẹn, in, ọn, un

A tún lè ṣe àtúnpín àwọn fáwẹ̀lì sí ọ̀nà méjì:

(I) Fáwẹ̀lì àìránmúpè (oral vowels)

/a/, /e/, /ẹ/, /i/, /o/, /ọ/, /u/. ní àdàkọ fóníìmù

[a], [e], [ɛ], [i], [o], [ɔ], [u]. ní àdàkọ fọ́nẹ́tíìkì

(II) Fáwẹ̀lì àránmú pè (nasalized vowels)

/an/, /ẹn/, /in/, /ọn/,/un/. ní àdàkọ fóníìmù.

[ã],[ɛ̃], [ĩ],[ɔ̃],[ũ]. ní àdàkọ fònẹ́tíìkì.

Ìró Kọ́ńsónáǹtì (Consonants)

Ni ilana foniimu:

/b/, /d/, /f/, /g/, /gb/, /h/, /j/, /k/, /l/, /m/, /n/, /p/, /r/, /s/, /ṣ/, /t/, /w/, /y/.

Ni ilana fonetiiki:

[b],[d], [f],[g],[g͡b], [h],[d͡z], [k],[l],[m], [n],[k͡p],

[r],[s],[ʃ], [t],[w], [j].

Àpẹẹrẹ bí a ti ń lo fáwẹ̀lì àti kọ́ńsónáǹtì ède Yorùbá.

b. = bó (to peel)

bò (to cover).

d. = dá (to break or to beat as in wrestling)

dà (to betray, pour etc.)

f. = fẹ́ (to like, marry, to blow with mouse etc.)

fẹ̀ (to widen, wide, to puff up)

fà (to pull)



g. = ga (tall, high, etc.)

gá (a special way of expressing the discharge of excretion as in 'Mo lọ ṣe gá) I went to pass excreta) etc.

gb. = gbà (receive, accept)

gbé (carry, to live etc)

gbọ́ (hear)

h. = ha (to scrape)

he (to pick)

há (to share our something)

j. = já (to pluck, to cut (off))

jẹ (eat)

jó (to burn)

jọ̀ (to sift)

jọ (to resemble)

k. = ká (to pluck)

kà (to count)

kó (to pack)

kọ̀ (to refuse, reject)

l. = lá (to lick)

lọ̀ (to grind)

lẹ́ (to plant)

lẹ (to be lazy)

m. = mú (to take)

mu (to drink)

mù (to go our of sight)

n. = nà (to flog)

ná (to spend)

nù (to get lost, disappear)

p. = pa (to kill)

pè (to call, invite etc.)

pẹ́ (to be late (in attendance)



r. = rà (to buy, to get rotten)

rẹ́ (to cut)

rẹ̀ (to get tired or weak)

re (to pluck as in pepper)

s. = sè (to cook)

sá (to run away, to spread out something)

sẹ́ (to deny or to filter)

s. = ṣẹ̀ (to offend)

ṣẹ́ (to break)

ṣà (to to pick up one after the other)

w. = wá (to come, attend)

wà (to dig up)

wẹ̀ (to wash or dip in water)

y. = yá (to lend, or borrow)

ya (to tear)

yà (to draw, or to branch)

Ṣe àkíyèsí pé a lè lo àwọn kọ́ńsónáǹtì àránmúpè aṣesílébù (the syllabic nasal ('m' ati 'n')

báyìí: ń = ń ṣe

ń bọ̀

ń lọ

ń jẹ

ń kọ

ḿ = ḿ bọ̀ tàbí ń bọ̀

ḿ bẹ tàbí ń bẹ

Nígbà mìíràn, n ati l máa ń gba ipò ara wọn b:a.

Èmi li Olúwa

Èmi ni Olúwa

3. Ìró Ohùn (Tone)

Àmì ohùn ṣe pàtàkì nínú èdè Yorùbá nítorí pé èdè olóhùn (tonal language) ni í ṣe. Àwọn ọ̀rọ̀ wà tí a máa ń kọ bákan náà ṣùgbọ́n àmì ohùn ló ń jẹ́ kí a mọ ìyàtọ̀ wọn tàbí ìtumọ̀ wọn. Orí àwọn



fáwẹ̀lì ati kọ́ńsónáǹtì àránmúpè aṣesílébù ni a má a fi àmì sí.

nì ohùn mẹ́ta ló wà:

(i) Ohùn ìsàlẹ̀ [\] d:

Àpẹẹrẹ: bà, dè, rẹ̀, fò , rà, sè.

Ẹ̀bà, ọ̀dẹ̀, ẹ̀ṣẹ̀, ọ̀fọ̀, àrà, àsè,

à - kà - bà,

d: d: d:,

ọ̀ - dẹ̀- dẹ̀,

d: d: d:,

ì - ṣẹ̀ - lẹ̀,

d: d: d:,

ò - jò - jò,

d: d: d:,

à - kà - rà

d: d: d:,

(ii) Ohùn ààrín [-] r:

Àpẹẹrẹ: ba, dẹ, ṣe, ṣu, ru, run

Aya, ọdẹ, ase, iṣu, irun, ẹnu

A-ya-ba, Ọ-mọ-ge, a-gba-mi, ẹ-rẹ-bẹ

r.; r; r:,  r.; r; r:,  r.; r; r:,  r.; r; r:

(iii) Ohùn òkè [/] m:

Àpẹẹrẹ: bá, dá, fẹ́, já, ṣọ́, mú, wá,

Bọ́lá, Délé, Péjú, Jábọ́, Múyán

Dé-kún-lé; wá ní bí; Lá-ń- gbé,

m: m: m:,  m: m: m:,  m: m: m;

Àwọn ọ̀rọ̀ níbi tí ohùn méjì tàbí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ti jẹ yọ:

- Ìgbálẹ̀ (Broom)
- Alága (Chairman)
- Alágbára (The powerful one)
- Alápatà (The butcher)
- Déńdè (a name)
- Kangókangó (sound of the bell)



- Adámọlékun (a name)
- Ojúróungbé (a name)
- Ajáńlékokò (a name)
- Adéníyì (a name)

Àwọn àpẹẹrẹ tó jẹ mọ́ ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀

(a) apa - àpá - a mark

àpà - a prodigal

apá - arm

apá - a tree

(b) ilu - ìlú - town/city

ìlù - drum

(d) eye - ẹyẹ - bird

ẹ̀yẹ - honour

(e) ẹyin - ẹyin - egg

ẹyin (iná)- coal of fire

ẹ̀yìn - back

ẹ̀yin - you (2nd person plural)

(e) ẹgba- ẹgba - cane
ẹ̀gbà - bangle
ẹ̀gbà - palsy
Ẹ̀gbá - a Yoruba tribe of Abẹ́ọ̀kúta
ẹgbàá - 2000

(f) igba - ìgba - 200
ìgbà - period
igbá - calabash
igbà - rope used in climbing palm tree
ìgbà - time or period
ìgbá - garden-egg

(g) awo- awo - cult, secret
awò - glasses
àwo - plate
awó - guinea fowl

(ab) iwọ- ìwọ - you
ìwọ́ - umbilical cord



ìwọ̀ - hook
ìwọ́ - navel

(h) ọwọ- ọwọ́- hand
ọ̀wọ̀- respect
Ọ̀wọ̀- a town
ọwọ̀- broom
ọ̀wọ́- pair, peer or fleet, company of etc
ọ̀wọ́ - (dialectical) – a handful, a small portion

(i) ojo - ojo - coward
Òjó - a name
òjò - rain

(j) aba - àbá - suggestion
abà - village
àba - incubation
Abá - a town in Nigeria
àbà - stocks

Ìhun Sílébù

A lè lo àwọn àrokò wọ̀nyí láti fi ìhun sílébù hàn

F dúró fún fáwẹ̀lì

KF dúró fún àkànpọ̀ kọ́ńsónáǹtì (+) àti fáwẹ̀lì

N dúró fún kọ́ńsónáǹtì àránmúpè aṣesílébù

Bí ọ̀rọ̀ bá rí bí a ti wí yìí, sílébù lè jẹ́:

(1) Ìró ohùn kan tí ó lè jẹ́ F (fáwẹ̀lì ǹkan) tàbí N (kọ́ńsónáǹtì àránmúpè aṣesílébù).

Àpẹẹrẹ: (i) Ẹ wá

(ii) A sáré

(iii) N kò wá

Níbí ti E, A, N, ti jẹ́ sílébù kọ̀ọ̀kan nínú àwọn i – iii

(2) Àkànpọ̀ ìró méjì KF (Kọ́ńsónáǹtì + Fáwẹ̀lì)

Àpẹẹrẹ: Bẹ̀, rà; sè gbà

KF KF KF KF



Àwọn ọ̀rọ̀ onísílébù kan

Àpẹẹrẹ:

(i) jà (ii) fò (iii) rìn (iv) bò

KF KF KF KF

Àwọn ọ̀rọ̀ onísílébù méjì

Àpẹẹrẹ: (i) à-bọ̀

F--KF

(ii) à-sè

F-KF

(iii) o-yún

F-KF

(iv) o-kùn

F-KF

Àwọn ọ̀rọ̀ onísílébù – mẹ́ta

Àpẹẹrẹ (i) ò-kẹ́-rẹ́

F-KF-KF

(ii) à-bà-rá

F-KF-KF

(iii) ò- ké- té
F-KF-KF

(iv) à- pà- là
F-KF-KF

(v) ò-kùn-kùn
F-KF-KF

(vi) gó- ń- gó
KF-N-KF

Àwọn ọ̀rọ̀ oní sílébù mẹ́rin ati jù bẹ́ẹ̀ lọ

Àpẹẹrẹ: (i) a- lá- kà- rà
F-KF-KF-KF

(ii) a- lá- pa- tà
F-KF-KF-KF

(iii) kọ̀- ǹ- gọ́- rọ́
KF-N-KF-KF

(iv) o- ló- jú- o- ró- gbó
F-KF-KF-F-KF-KF

(v) o- ní- dù- ǹ- dú
N-KF



# ORÍ KEJÌ
## ÌSỌ̀RÍ Ọ̀RỌ̀

(1) Ọ̀rọ̀ - Orúkọ

Oríṣìíríṣìí ọ̀rọ̀-orúkọ ni:

(a) Orúkọ ènìyàn: b. a. Àjìkẹ́, Túnjí, Olúfúnkẹ́, Ọládélé, Ọládìran, Yẹ́misí, Àmọ̀ọ́, Ìṣọ̀lá, Ọmọ́wùnmí, Títílayọ̀, abbl.

(b) Orúkọ ìlú, ibi kan, ibùgbé abbl:
Èkó, Orílé-Ìgànmú, Ìjàníkin, Abẹ́òkúta, Iléṣà, Ọdẹ́dá, Òpópónà Balógun Parapọ̀; abbl.

(d) Ọ̀rọ̀-orúkọ ohun ẹlẹ́mìí/abẹ̀mí
Àpẹẹrẹ: Ènìyàn., ẹranko, ajá, èèrà, ejò, igi,ìrókò abbl

(e) Orúkọ ohun aláìlẹ́mìí
Àpẹẹrẹ: aago, omi, ẹ̀pà, pátákó, abọ́, ìfẹ́, ìgò, iná,òkò, àdá, abbl .

(e) Orúkọ ohun àrídìmú
Àpẹẹrẹ: aago, pátákó, ìgò, ẹ̀pà, òkúta, tábìlì, abbl